



# Irohin Yoruba

A Newspaper of the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd

VOL. XII NO. 593. OCTOBER 22—OCTOBER 28, 1956. KOBO MEJI (2d)



VOMICURE

FUN ABA-YIYA ... VOMICURE.

EJIWUNMI MEDICINE STORES

8, Ojulegba Street, LAGOS


# IJỌBA GẸẸSI GBA FUN IJỌBA IWỌ-ORUN LATI GBA OMINIRA

Ni arọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni irohin de gbukẹ pe Ọlọla Alan Lennox—Boyd Aṣoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn ilu amọna Ijọba Gẹẹsi fi iwe eto ipade awọn Oṣelu Naijiria ṣowọ si Gomina—Agba Apapọ Ijọba Naijiria pe awọn ti gba lati fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni Ominira ati pe ni Lọndọnu ni awọn o ṣe ipade pataki na ninu oṣu kini ọdun ti mbọ yi. O si ni ki Gomina—Agba Naijiria na o fi eto na si etigbọ gbogbo awọn Alaṣẹ Ijọba Ipinlẹ kọọkan ti o wa ni Naijiria ati Kamẹruu, ki o si gbọ esi olukuluku Ijọba Ipinlẹ na wa fun on lori eto ipade na.

Gẹgebi iwe eto Ipade Pataki na ti Ọgbẹni Lennox-Boyd fi ṣowọ si Gomina-Agba Naijiria ti ṣe lo ṣẹṣẹṣe niyi:—

O ni nigbati on nṣo ipinnu on fun Apapọ Igbimọ Ijọba Gẹẹsi (Parliament) ni ilu Oyinbo ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu keje ọdun yi pe on ni lati yan Igbimọ Oluwadi fun ibadupọ ti o wa larin Dọkita Azikiwe, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ati African Continental Bank. On si ṣe alaye gbangba nigbana pe Ijọba Gẹẹsi si duro lori adehun ipade 1953 pe Ijọba Ipinlẹ Naijiria ti o ba fẹ ominira awọn o fun un.

On si ṣe alaye bi o ti ṣe je pe eto Igbimọ Iwadi African Continental Bank na yio mu ki awọn sun ọjọ ipade apero na siwaju diẹ si.

O ni nisisiyi awọn Igbimọ Iwadi Banki yi ti mba iṣẹ wọn lọ, awọn si ti fi oju da a pe ki eto iwadi na to pari, a to ipari oṣu kọkanla ọdun yi. Nitorina a le fi akoko si Ipade Apero pataki na nisisiyi; ati wipe Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti pinnu lati ṣe idibo ninu ọdun yi ti ko ni le pari titi di ipari ọdun yi.

O ni lati fun gbogbo nkan wọnyi laye, on ri wipe asiko ti o tọ ti awọn le fi eto Ipade Apero na si ni ibẹrẹ

Wo oju ewe kẹfa



Ọlọla Alan Lennox-Boyd, Aṣoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn ilu amọna Ijọba Gẹẹsi.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria.

## Ẹgbẹ Ọmọ - Oduduwa Ṣe Ajọdun Kẹsan

PẸLU ọpọlọpọ idunnu ni awọn aṣoju ipade ajọyọ Ẹgbẹ Ọmọ-Oduduwa na fi gba irohin Ominira ti Aṣoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn ilu amọna Ijọba Gẹẹsi so pe didun inu Ijọba Gẹẹsi ni lati fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni Ominira.

Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni awọn ṣe ipade ajọyọ Ajọdun kẹsan Ẹgbẹ Ọmọ-Oduduwa, ni Sagamu. Oloye Dọkita Akinọla Maja si fi tayọ-tayọ ki gbogbo iko Ipade Ẹgbẹ na kuabọ ati ku ori're. O ni Ibo ti nwọn di fun awọn aṣoju Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun kọja yi, ohun ti a le fi ṣe apejuwe rẹ ni pe bi okun-pupa ti ri fun awọn ọmọ Israeli nijọ kini bẹ e gan an ni o ri fun awọn enia Ipinlẹ IwọOrun.

Lehin ti awọn ara Ipinlẹ IwọOrun ti re okun-pupa kọja tan ni nwọn wa nri Kenaani, Ilẹ-ileri wọn lọkankan. Eri eyi ni ọrọ ti Aṣoju Ijọba Gẹẹsi ni ilu Oyinbo so nipa yiyonda Ijọba-ominira fun Ipinlẹ na.

Ninu ọrọ iranti Baba Ẹgbẹ na bi o fun mu ẹnikan ọrọ asọkẹhin Baba Ẹgbẹ atijọ, Ologbe Ọlọla Adeyẹmọ Alakija pe o so bayi pe: "Ominira fun orilẹ-ede Yoruba ti ara han l'orere, bi emi on ko ba tilẹ gun de asiko ti nwọn yio fi gba a, ninu ayọ wipe on ti ri i l'orere ni on yio ku si."

Ọlọla Adeyẹmọ ko ni ifura rara wipe akoko-ikẹhin on sunmọ etile nigbati o nsọrọ wọnyi, ṣugbọn titi aiye ni a o ma a ranti iwa akikanju rẹ ninu itan orilẹ-ede Yoruba. Ipade na si dide-duro ni idakẹ jẹ e fun iṣẹju meji ni iranti Ologbe akikanju Baba-ẹgbẹ na.

Oloye Dọkita Maja tun ran wọn leti pe lati igbati Ọlọla Adeyẹmọ Alakija ti ku ni ẹru aṣiwaju ti bọ si ejika on ani bi o ti ṣe bọ

Wo oju ewe kẹwa

## Gomina ati Alakoso Ila-Orun lọ di si ara wọn

ỌLỌLA Clem Pleass Gomina Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria ati Dọkita Nnamdi Azikiwe, ti iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun lodi si ara wọn nitori esi ti nwọn fi ṣowọ si Ọgbẹni Lennox-Boyd Aṣoju Ijọba Gẹẹsi fun awọn ilu amọna Gẹẹsi lori ipade ti nwọn fi si oṣu kini ọdun ti mbọ ni Londọnu ati Ominira Ijọba ti nwọn fẹ yọnda fun Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Esi ti Azikiwe ni pe on ati Igbimọ Ijọba on ko ni le ri aye a ti wa si Londọnu ni asiko oṣu kini ọdun na nitori owo awọn yio di fun a ti ṣe eto inawo Ijọba fun ti ọdun ti mbọ na ati wipe ni ilẹ yi (l'Eko) ni on faramọ pe ki nwọn ṣe ipade na ninu oṣu kejila ọdun yi.

Dọkita Azikiwe ni ibu on dun si ti wipe nwọn yio fun Ijọba Ipinlẹ Naijiria ti o ba fẹ gba Ominira ni Ominira ṣugbọn ni ti Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ohun ti awọn fẹ ni pe ki gbogbo Apapọ Ijọba Ipinlẹ Naijiria o gba Ominira papọ ... ọdun 1959.

Alaye ti Gomina Ipinlẹ Ila-Orun na ṣe ṣowọ ... Aṣoju Ijọba Gẹẹsi na ni ilu Oyinbo ni pe esi ọrọ ... kiwe ki iṣe ohun ti a le ... ni on Igbimọ Ijọba Ipinlẹ

Wo oju ewe kejila

## Ọwa Ilesha w'aja

ILẸSA

AGBO-JUGBA-NU ni iro iku Ọba Alexander Adesumọla Haastrup, Ajimoko Keji, Ọwa Ijẹsa je fun gbogbo ara ilu Ijẹsa ati awọn ti nwọn wa ni agbegbe ilu na ni Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu kewa ọdun yi, nigbati o di ẹsa ọgọrin ọdun l'aiye. Fun ọsẹ diẹ ni o ti ṣe aisan.

Ni ọjọ kejila oṣu kewa ọdun 1942 ni nwọn fi je Ọba. O je okan ninu awọn aṣiwaju ninu Igbimọ Ijọba ... on si ni Alakoso Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ijẹsa nigba aiye re.

Awọn iyawo rẹ je mẹdogbọn, o bi adọta ọmọ ati ọpọlọpọ ọmọ-ọmọ ti nwọn nṣe'hin de e loni. Ọgbẹni A. Ojo Haastrup ti 4 Chapel Street, Eko, ni akọbi rẹ ṣaba.



# EYI NI OJO AWON OJA ILE WA.

### OJO AJE 22ND OCTOBER (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Oyingbo. Ejinrin. |
| Abeokuta. | Ijoko, Iberekodo, Asa, Wasinmi. |
| Ibadan | Ogunjana, Lagun, Sagbe, Olode |
| Ijebu | Aiyepe Sagamu Itaosu Ogere Irolu, Ibele, Ita-Iloti |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha Ibodi Ibode Kajola. Oluwa'da. |
| Ondo ati Eti Odo | Oka Ilara. Abigi. Aiyetoro. Epe |
| Egbado | Alagba Ilaro Sunwa Iboro Jigga |
| Ogbomosho | Obada Gambari. |
| Ekiti | Ilogbo. Oke-Aiyedun Idogun |
| Ibinni | Eko |
| Delta | |
| Igbajo | |

### OJO ISEGUN 23RD OCTOBER (TUESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Obun Eko |
| Abeokuta | Atan Agbado Ilo Itoku Isabo Odeda, Ibara, Itori |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iresi Obada Egbeda, Oyedeji |
| Ijebu | Ilishan Odogbolu, Atan Imope Ishan Isara, Imodi, Ajegunle |
| Ijesha | Esa-Oke Ilase Epe Iloba Iperindo, Imuroko, Erinmo. |
| Ondo ati Eti Odo | Odojomo Igbotako, Ilepluji Obunkekere Agirifon-Ilutitun |
| Egbado | Aiyetoro Tata. Rando, Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iresa-Du. Arolu Egbeda |
| Ekiti | Igosi. Odo-Aiyedun. |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajo | |

### OJO 'RU 24TH OCTOBER (WEDNESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Mushin. |
| Abeokuta | Owode Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo Owowo Obafemi Oja-Ojo |
| Ibadan | Ikenne Okun-Owa Eruwon |
| Ijebu | Omu, Ago-Iwoye |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha Oshu Itagu Odogbo, Iloko, Ipetu, Owode, Idoko. Agbabu Igbogi. Ishaa. Erinkela |
| Ondo ati Eti Odo | Olorunda. Kajola. Iloba Eredo |
| Egbado | Araromi. Iregba |
| Ogbomosho | Erekesan |
| Ekiti | Osele |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Ilogo |

### OJO 'BO 25th OCTOBER (THURSDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Agege. Ikeja Ebute-Ero. Ojo Ajido |
| Abeokuta | Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle, Idogo, Ogumaki, Itori |
| Ibadan | Ibuko Lalupon |
| Ijebu | Ibefun, Atikori, Imushin, Ijesha-Ijebu, Isara, Imodi, Ipara. Mamu |
| Ijesha | Esa-Oke. Iware. Ejioro. Odo Ibokun, Esa-Odo, Ijeda, Ikeji |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren, Atijere. Oni Ebiwo. |
| Egbado | Idi-Emi. Ibeshe. Lasilo, Atta |
| Ogbomosho | Oko |
| Ekiti | Ifaki Okemesi |
| Ibinni | Uromi |
| Delta | |
| Igbajo | |

### OJO ETI 26TH OCTOBER (FRIDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Oyingbo |
| Abeokuta. | Ijoko, Iberekodo, Asa, Wasinmi |
| Ibadan | Olode. Ogunjana Lagun. |
| Ijebu | Aiyepe. Sagamu Ita-osu Ogere Irolu, Ita-Iloti, Ibele, Oyingbo. |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha Ibodi Ibode Kajola, Oluwa'da Ita-Apa |
| Ondo ati Eti Odo | Abigi, Aiyetoro. Oka Ilara Epe |
| Egbado | Alagba Ilaro Sunwa Iboro |
| Ogbomosho | Obada Gambari |
| Ekiti | Ilogbo. Oke-Aiyedun Idogun |
| Ibinni | Eko. |
| Delta | |
| Igbajo | |

### OJO ABAMETA 27TH OCTOBER (SATURDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Obun-Eko |
| Abeokuta. | Atan, Agbado, Ilo, Itoku Isabo Odeda, Ibara. |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iresi Obada Egbeda. Oyedeji |
| Ijebu | Ilishan Odogbolu, Atan Imope Ishan, Isara, Imodi, Akesan |
| Ijesha | Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko, Erinmo, Esa-Oke |
| Ondo ati Eti Odo | Agirifon-Ilutitun Odojomo, Igbotako, Ilepluji. Obunkekere. |
| Egbado | Aiyetoro Tata. Rando. Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iresa-Du. Arolu Egbeda Jabata. Oke Ishale |
| Ekiti | Igosi. Odo-Aiyedun |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajo | |

### OJO AIKU 28TH OCTOBER (SUNDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Mushin. Badagry |
| Abeokuta | Otta. Abalabi. Sodeke, Owode. Omida Ilawo Owowo Obafemi Oja-Ojo |
| Ibadan | Ikenne Okunowa. Eruwon |
| Ijebu | Omu, Ago-Iwoye |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha, Osu. Itagu. Idoko Iloko, Odogbo, Owode |
| Ondo ati Eti Odo | Ishaa, Aye Erinkela Agbabu Igbogi |
| Egbado | Iloba. Igbooria. Ijoun Imasai |
| Ogbomosho | Araromi. Iregba |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Iloro |

### OJO AJE 29TH OCTOBER (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe re | Agege. Ikeja |
| Abeokuta. | Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle, Idogo. Ogumaki |
| Ibadan | Lalupon. Ibuko |
| Ijebu | Isara Imodi Ibefun Atikori Imushin, Ijesha-Ijebu, Mamu Ijesha-Ijebu, Ipara |
| Ijesha | Esa Oke Iwara Ejioro Odo Ibokun, Esa-Odo |
| Ondo ati Eti Ondo | Igbo-Egunren |
| Egbado | Idi-Emi. Lasilo, Igan-Okoto, Atta |
| Ogbomosho | Oko. |
| Ekiti | Ifaki Okemesi |
| Ibinni | Uromi |
| Delta | |
| Igbajo | |

## ITUMO ALO

1. Ojiji.
2. Aja (ceiling)
3. Iga
4. Ake, Obelo, Ifele
5. Ilu.
6. Ilu-ilu.
7. Iyo.
8. Eyin-iwin
9. Ojo-oni
10. Igbaleke-ara-ile.

## Igbeyawo Karimu Oşimo dun

KOSSI:

NI ojo Aje ti ooe ojo kedogun osu kesan odun yi ni Karimu Osimo gbe Omidan Asiawu Adegbola ni iyawo Fona esin Musulumi. Oko iyawo na ati owo bem Gabriel Mojoyin egbon oko iyawo na ko si rebin nimu inawo ojo na. Nitoto ni ti jije te awon alabaseye won lorun.

Die ninu awon alabaseye ojo na ni awon Ogbeni Ilaji Alani akowe Egbe Afenifere oka Iragun M. F. Falade Moses Ojeniyi S. A. Ojekunle, Samuel Ojedayo James Ojeleye ati Egbe oko iyawo ti nje "Kokoro-aiye".

Ire a kari o.









# OGBẸNI E. O. ẸYỌ TI BẸRẸ SI SỌRỌ


AWON OGBOLOGBO

(SCRAP)

OJE (LEAD)

IDẸ (BRASS)

BABA (COPPER)

AWỌN ALOKU IRIN

ẸRỌ MỌTO (RADIATORS)

PAANU AYỌ (ALLUMINIUM)

JE OWO

Ko wọn wa ta fun

BUCK (NIGERIA) LTD..

2. AERODROME ROAD, APAPA.

TELEPHONE

55177.


NI ọjọ Eti'ti ṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Ogbẹni Effiong Okon Ẹyọ ti o ti ti iṣe kan



OGBENI E. O. EYỌ

je Alaga Igbimo Amulada-gba Ijọba Ipinle Ila-Orun (Eastern Regional Development Corporation) o si tun je Adiṣangan Egbe NCNC ninu Igbimo Ijoba Ipinle Ila-Orun ati Gbekeji Alaga Igbimo na bere si jeri niwaju Igbimo Iwadi oran ajumoṣe Dokita Azikiwe pelu African Continental Bank.

Ogbẹni Eyo yi ni eniti o mu ọrọn Dokita Azikiwe ti ṣe Alakoso Igbimo Ijoba Ipinle Ila-Orun wa pe ajumoṣe re pelu African Continental Bank ni makaruru ninu ti o si fi si iwaju Igbimo Ijoba Ipinle Ila-Orun pe ki Ijoba o yan Oluwadi si oran na ti Alaga Igbimo Ijoba Ipinle Ila-Orun si ko fun un. Ki o to di pe oro yi de odo awon Alakoso Ijoba to ju Ijoba lo.

Nigbati Ogbeni Eyo bere si soro niwaju awon Igbimo Iwadi na, pataki eri re ni wipe, gegebi ipo aye ti on dimu laseko na ninu Igbimo Ijoba Ipinle Ila-Orun, Dokita Azikiwe ni o so fun on lati se eto bi owo Ijoba na ti se di ohun ti awon o ko lo si Banki re.

Bi Ogbeni Frank Beakley, asiwaju awon agbejoro Azikiwe ti nfi oriṣiriṣi ibere si iwaju Ogbeni Eyo lati fi mo boya adaboni ara won ni, Azikiwe ko ni owo nibe, beni Ogbeni Eyo si nfi a lohun pe Azikiwe lowo nibe, o ni eṣe nibe pelu, o si ṣe alaye bi imoran ti aiṣe nko larin Ogbeni Ojike ati Azikiwe ati on nk.

Ogbeni Eyo si ṣe alaye pupo lati fi han pe Azikiwe lowo nibe, ninu alaye na ti o gbe fi han fun awon Igbimo Iwadi pe nigbati Alakoso Ijoba Ipinle Ila-Orun akoko Ogbeni Eyo Ita ko gba imoran Azikiwe lati gbe owo Ijoba na lo si African Continental Bank ni nwon ba fi bere si ta kanrangbon si ara won titi nwon fi tu Igbimo Ijoba Ipinle Ila-Orun akoko na ka.

## Ominira fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun

*Lati oju ewe kini*

odun ti mbọ.

O ni on fẹ lati ṣe Alakoso Ipade Apero na titi awon o fi pari rẹ, nitori on ko fe ki idiwọ kankan o wa fun on lati ma wa si Ipade Apero na; ati wipe ki awọn Olotu Ijọba Naijiria faramọ imoran akọko ti a da pe ni Londọnu ni a o ṣe e, ki nle ri aye mojuto gbogbo rẹ.

O ni on si fẹ lati sọ pe Ijoba Geesi tị mura tan nisisiyi lati yonda Ominira Ijoba fun Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ati olukuluku Ijọba Ipinlẹ Naijiria ti o ba ti mura tan lati gba Ominira, pe ti gbogbo eto Ominira ko ni jẹ ifarapa fun Apapo Ijoba Naijiria a ti lati mu gbogbo eto ti o je pataki ninu Ipade Apero 1953 ṣe.

O ni inu on a dun bi awọn Olotu Ijọba Naijiria ba le tete fi eai won ran Gomina Agba Naijiria si on gegebi olukuluku Ijoba Naijiria ba ti ro pe eto Ipade Apero na ti bọ si i si.

## *Gomina ati Alakoso Ipinlẹ Ila-Orun*

Lati oju ewe kini

Ila-Orun, nitori eai ti o fi si fifun Ijoba Ipinle Iwọ-Orun ni Ominira ko yanju.

O ni nitorina on (Gomina) tun bi i lere pe ki o soro na ki o yanju dada. Sugbon eai ti Azikiwe fi da Gomina Ijoba Ipinle Ila-Orun na lohun ni pe ki Gomina na ye e ṣe ayonuso si ọran ti ko kan an.

## Ọpọ enia f'Ẹgbẹ N.P.C. silẹ

ILORIN

EKA Egbe Olomi (Northern People's Congress) ti Ilorin bereai subu, awọn igi-lehin-ogba Egbe na ko ba won ṣe mo. Nigbati Egbe Talaka-Parapo afapọ mo Egbe Afenifere ṣe ipade ikede-ibo (campaign meeting) lenuloloyi ni adugbo Olomo'ba, awon mejileladorin omọ Egbe Olomi (NPC) ni nwon wọ Egbe Talaka-Parapo na.

Mallam Buraimo Dan Sofo, asiwaju awon mejilelaadorin na ti o fi Egbe NPC silẹ so fun odegbaata awọn enia ti o pejo sibẹ lati gọ idi abajo pe idi ti awon fi kuro ninu Egbe NPC ni pe Egbe na ko ni ife si awon alaini.


MERCEDES-BENZ



THE 5/6 TON LORRY FOR

★ RELIABILITY AND LONG LIFE

★ LOW FUEL CONSUMPTION

★ HIGH PERFORMANCE

WITH A FULLY ORGANISED "AFTER SALES" SERVICE

AT MODERATE CHARGES

SUPERVISED BY EXPERT ENGINEERS FROM THE MERCEDES WORKSHOPS.

LEVENTIS MOTORS

DISTRIBUTORS FOR NIGERIA


Printed and Published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 5/7, Apongbon Street, Lagos (Editorial and Advert. offices) Tele. 20658, 20[illegible]. Fun Owo Irohin Yoruba [illegible] kan:—Eko-nile mejo ati kobo mejo (8s. 8d.) fun iditan ni Nigeria ati Oke-Okun [illegible] Olotu E. M. Adeniyi[illegible], 8, Chapel Street, Lagos.

# Owe ilẹ Yoruba

1. Bi ile ko ba kan ile ki i jo ajorun.

2. Bulu a o ki ko won, enihi a ba ki ko tara je ni.

3. Ohun je mo tire giri ti ara ọdẹ ni fila ni l'ara.

4. Ijo ifita je igba o o bu ... a si bati ara enit.

5. Lọbalaba ti o ba ... Tepin woo re a fagia.

6. Ngu se iya ko le jo ... ngu so badia ko le je ...

7. La ojo ere lọwan idun ... ifa wọle ko jade; a da ko roṣi a pope pasrapa.

8. Odin mọ o wẹ inu kodi ẹtve oko.

9. Okere je eyin, o yo ... ohun ti a wo je la a-we.

10. Palapala fa faye. ... kumana l'a dede; oju ... ipa ni I da ede.

11. T'owo ni t'ẹnu, ẹgbin ni ti nafun.

12. Ero amukun ti o wọ ... ile ni o ti wọ wa.

13. Wara ko si loni. ... wa lola.

14. Gagirine ti a pe ko ... Ijoba ye, eni na ni i mba ... je.

15. Obajumo ju owo lọ.

16. Ero oko ba ti i mọ oko, enia bi obo ni obo nja ...

17. Bi ma ba je oko a ... fun alubi.

18. Kai kese, ola ijanu, ... die Pesin nkn.

19. Hun-hun gbe ikun, ... ko dunmo ko gbalo ... nitori Ise Oluwa ni.

20. Wo ọmọ de mi nlo kijuba mẹta gbo, melo ni obinrin paapa yio lo gbo o?

# ALỌ O? ALỌ!

(Lati ọwọ Mudasiru Olalere Ajala—Methodist School, Iṣẹ, P. O. Box 24.)

1. Bin-tin yin-un, a dun ma b'ẹpo.

2. Eni oba, a le ka.

3. A gbe arugbo gun igi, a ti so o di ija.

... Agbagba mẹta fi oru... ara wọn.

... A ge e l'ori, a ge e ... o tun nke lo si afin.

... A bi ọmọ l'oni, o si fi ... joko.

... Nana ikukuru le'pa ...

... Otiriki, ile oba ko ... ...

8. O le wẹ, ko to nu.

9. Ọja na Oniroṣun, ko ... Ifalogun.

... ojo ewe kohunla

# Iwe si Olotu Irohin Yoruba

# Nko jẹ'nikan l'owo, kọbọ!

## Ẹgbẹ Agbẹ ndupẹ

MO fẹ dupẹ ni gbolohun kan fun iranlowo nlanla ti Ijọba Afẹnifẹre nṣe fun awa agbẹ. Ko si iṣẹ kan ni gbogbo Akoko ti Ijọba ko ti ṣe eto lati ma a ṣe awa agbẹ lowo. Iranlowo pupọ ni eyi je fun gbogbo wa. Eyi fi han wipe Ijọba wa gan an ni Ijọba ti oni. A dupẹ o. Ni aruku gbẹrẹ awọn agbẹ apbegbe Akoko ni mo fi ndupe.

Emi ni,
SOLOMON FALADE
Ikare.

AWON enia mbere lowo mi pe eṣe ti mo fi kuro ninu Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC). Jeki ngkoko so eyi na bi alaye: ngko jẹ enikan lowo ninu Ẹgbẹ Alakukọ. Igbati o wa mi ni mo wọ ẹgbẹ na, nigbati o si wu mi ni mo yọ ara mi kuro ninu rẹ. Kinni ija ninu ogundareke? Ogun ni o ni ireke rẹ, Ogun na ni o si da a. Emi ni mo ṣa ni ara mi, Ẹgbẹ Alakukọ ko wo fun mi mo. Idi niyi ti mo fi yọ kuro ninu rẹ.

Boya ori buruku ni mba awọn alakukọ ja ni, boya alwo-iwa-hu ni, emi ko mo. O daju wipe ọkan ninu mejeji ni mba wọn ja. Ijọba wọn ndaru loke. Ijọba awọn ndaru ni isale. Nibigbogbo ni idaru yi wa fun awọn alakukọ. Ni Ila-Orun iyọnu, ni Iwọ-Orun iyọnu. Ko si si ohun ti awọn so fun wa ri ti a ba ṣẹ. Oni eje, ola ijangbam. Nje bi ẹsu ko ba pada lehin eni a ma a pada lehin eṣe ni.

Emi ni,
LAWANI A. FATUNMBI.
Ibadan.

## A ko ni anfani Ile-Ẹkọ giga ni Ipinlẹ yi

INU mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye lati so ọdun okan wa fun gbogbo aiye gbo ninu Iwe "Irohin Yoruba" ti ise alagborandun fun gbogbo orilẹ-ede Yoruba.

O jẹ mo pe gbogbo ariwa ti awọn npa ni Ipinlẹ Ariwa, ko si ile-ẹkọ giga kan fun wa lati lo ko ẹkọ. Opolopo ẹlẹgbẹ mi ti o jẹ ọmọ ile-iwe ti a si ti pari ẹko wa ni ile-ẹkọ kekere ni a nfe wa ko ẹko giga ni Ipinlẹ Iwọ-Orun gbogbon ko si aye fun wa.

Mo fe ti ita je pe ki awọn obi mi fi ibujoko wọn si Ipinlẹ Iwọ-Orun ki a le je alabapin anfani ẹko giga ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun npese fun awọn enia abẹ Ijọba rẹ.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi o.

Emi ni,
A. GANIYU ADIO.
Ilorin.

## A dupẹ lọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre

NKAN kan pataki wa ti mo fẹ dupe lowo Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) fun. Ase awa enia dudu paapa le se Ijọba lori ara wa ki Ijọba na si ma a lọ daradara? Ohun iyanu ni ohun ti a nri loni. Pupọ awọn ilu ni ile wa ni Oyinbo ko de lati nkan bi ọdun mẹta sẹhin. Pelu aidebẹ awọn Oyinbo, Ijọba si nlo deedee. Ki a dupẹ lowo Olorun fun ohun ti O fun wa ti a ko mọ wipe a ni yi.

J. K. ARIFALO
Owo.

## A nfẹ Radio, ẹ jọwọ

KINNI oko ti ẹ fi se ori ti Imaki ko fi se? Nwọn ni redio ni Oshogbo. Nwọn ni ni Ede. Nwọn ni ni Iwo. Bẹẹ ni nwọn na ni Ogbomoso. Tiwa ti jẹ ni Ejigbo ti a ko fi ni?

A ko ti i ni ina lẹntiriki ti yio fi wa sinu imọle. Bi enia ko ba riran, o ha yẹ ki eti re tun di? Bi a ko ba ti i ni ina ko ha yẹ Ki a ni redio ti so ita fi eti gbo? A ke bebe wa Ọba Elejigbo, ki o ba wa ba awọn alaṣẹ sọrọ ki nwọn ba wa mura si ọrọ redio yi. Odumare ko ni jẹki eti gbogbo enyin onkawe Iwe "Irohin Yoruba" di. Ilu ti redio ko ba si kuni diẹ ilu aditi. Awa na fẹ redio o.

Emi ni,
SAMUEL O. LADITI
Ejigbo.

## Oloye Akintọla ẹ gba wa

KINNI se ti a ko ti i ni ẹro asoromagbesi (radio) ni gbogbo Iyedade ati Egbedore? Awa na ni owo lowo ti a nan anfani awọn ara ilu ti nwọn gbe ni redio ti ni owo lọwọ ti nwọn nsan. Ese ti awa ko ti ti i ni anfani nlanla yi? O yẹ ki awọn oniredio tete da wa lohun.

A be Olola S. L. Akintọla ati awọn ajọṣu wa bi Olola Ogunmuyiwa ati Olola Oyedeji ki nwọn tubo ba wa mura si ọrọ redio yi. A dupe fun ohun rere gbogbo ti nwọn ti ṣe fun wa sẹhin. Ki nwọn tubo te siwaju. Ire ni nwọn yio ma a ri o.

Emi ni,
M. O. KỌLAWỌLE
Ikire.


# M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T. dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sárẹ́ òyì pẹ̀sẹ̀jẹ̀. Àlá búburú wọ̀ gbó. Àìlèsùn r'ẹ̀hìn-ẹ̀kùn. M.B.T. l'ògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun b'ìkàn, amú ni yágbẹ́ bí òkùn, amú ni tọ̀ bí àkèrè. Abiwẹ́rẹ́ f'áboyún, agbẹ̀jẹ̀ di f'awọn abiyamọ. Ahọ́n-dúdú, ẹ̀sẹ̀-wíwú ati àìyà-jíjá ko si pẹ́nìtì nlo o. 4/6 pẹ̀lú 1/6 owó-ọkọ̀.

ARADAN STORES P.O.Box 2, EBUTE-METTA.





# Irohin Yoruba

ẸSIN ỌRỌ WA:—IWAJU L'ỌPA EBITI NRE SI

Fun owo "Irohin Yoruba" ọdun kan

Eko—sile mejo ati kobo mejo (8s. 8d.)

Ilu miran ni Nigeria ati Oke Okun sile mẹtala (13s.)


## ỌRỌ-OLOTU

## ITANṢAN OMINIRA TAN JADE

A KI awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre ku ori're, paapa awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati paapa-julọ Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre. A ki gbogbo wọn ku ori're lati isalẹ de oke laida ẹnikan si.

Ohun ti o mu wa ki awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ku ori're ni irohin ayọ ti o jade niwaju iwe wa ọsẹ yi pe Ọgbẹni Alan Lennox-Boyd Alamojuto awọn ilu abẹ Ijọba Gẹẹsi, ti o ranṣẹ si Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria pe ki ẹlyẹ ile o gbọ ko sọ fun t'oko pe Ijọba Gẹẹsi ko yẹ adehun lati fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni Ominira.

O ni gẹgẹbi adehun ti awọn ṣe ninu Igbimọ Ajọro ti 1953 ni Londọnu ati ti ibẹrẹ ọdun 1954 l'Eko pe Ijọba Ipinlẹ ti o ba fẹ gba Ominira ti o ba si yẹ bẹ ẹ, awọn o ṣe eto rẹ lati fun un. O ni gẹgẹbi awọn si ti nwo ibẹwosi awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun pe nwọn ko jafara si iṣẹ idagbasoke ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun rara, nitorina ninu Ipade Igbimọ Apjero ti nwọn yio ṣe ni ibẹrẹ oṣu kini ọdun ti mbọ yi ni Londọnu ni awọn o pari eto na.

## ỌKIN MỌỌ'WỌ INU MB'ẸIYẸ OKO

BI irohin yi ti jẹ ayọ fun awọn olufẹ Afẹnifẹre, ti nwọn fẹ otito ti nwọn ko fẹ itanjẹ, bẹẹni o jẹ ibanujẹ fun awọn ẹni-okunkun, awọn aturọta-bi-elubọ, awọn arijẹ-ni-madaru, ti nwọn nsọ wipe "Kosi nkankan nibẹ" ọrọ wọn ko le jọ wa l'oju: "Anjuwon ko ṣe wi l'ẹjọ ni ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ija Ilara ko tan bọrọ."

Ẹ ti ibi iṣana kiyesi oogun, nigbati nwọn lọ ṣe Ipade Igbimọ Apero yi ni Londọnu ni 1953, Ọgagun Ẹgbẹ Alakuko (N.CN.C.) Dọkita Nnamdi Azikiwe ti iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ,wa pelu wọn nigbana ti nwọn ṣe eto pe ki Ipinlẹ ti o ba fẹ gba Ominira ninu ọdun 1956 ki o bere, awọn o fun un, Azikiwe faramọ o nigbana.

Nigbati o di pe Omniira Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fẹ bọsi kiakia, Azikiwe pa ohun da, o ni ki gbogbo awọn o duro gba a papọ ni 1959 ni on tun duro de. Kini nda Azikiwe duro o? Hun-hun-hun—bi a ba pe "mọ ọ omoran a mọ o" aimọṣe ni. Ko si nkan meji ti nda a duro ju aimete aimero ti i mu ọmọ iya mẹfa ku s'oko ẹgba ẹgbaafa lọ. Nwọn ni ẹlyẹ Operẹ o ko duro ko ifa ko yẹ ọ, o ni "mọ mọ ọbara, mọ m'ofun, mọ mọ ọbara mọ m'ofun". Ko ba tan bi ?

Ile ti a ba fi ito mọ iri ni yio wo o. Kini nda Ẹgbẹ Alakuko laamu ? Ais'oto, anikan-jopon, imọtaraẹni-nikan. Arun buruku ni eniti ko mọ nkan ṣe ti o sọ pe on mọ o ṣe ju ẹniti o mọ ọ ṣe lọ, ibiti ais'oto usin enia de ni o usin Ẹgbẹ Alakuko lọ ti ẹ nri yi. Nwọn ni Ijọba ti nwọn di 1959 ki o to gba Ominira, tani ko ti mọ pe nwọn ko to bẹẹ bi waka (orin) awọn Imalẹ ti o ko bayi:—

> Aṣa nfo fẹ e
> Awodi nfo fẹ e
> Rikiṣi ko j'adiẹ o fo fẹ ẹ
> Rikiṣi ko j'akuko o fo fẹ ẹ
> Rikiṣi ko j'akuko o fo fẹ ẹ.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre ẹ ku ori're. A ko ni ṣe e ti, laif'ọta pe Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre ngba Iwaju, iwaju-waju l'ọpa ẹbiti i re e si.

## Bi Ijọba ominira o ti jẹ fun Ipinlẹ Iwọ-Orun

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejila oṣu kejila ọdun ti o koja yi nigbati nwọn ṣe ipanu ninu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria pe o tọ o si yẹ pe ki Iwọ-Orun wa laye Ominira, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe alaye bayi pe nigbati Ipinlẹ Iwọ-Orun ba wa laye Ominira, Ipinlẹ na yio ni agbara gan an lati ma a da gbogbo eto Ijọba rẹ pe lai jẹ pe yio ma a gbe awọn eto Ijọba rẹ ria lọ ba awọn alaṣẹ ilu miran pe ki nwọn fi ọwọ si i ki o to bọ si lilo.

Wonyi ni awọn eto ofin pataki ti nwọn daba lati ṣe:

(a) pe aṣẹ Ọba Gẹẹsi ni nwọn o ma a fi yan Gomina wa lẹhin ti Alakoso Ipinlẹ ba ti ni ohun si i tan

(b) pe Gomina yio fi aye Alakoso Igbimọ Iriju Ijọba (Executive Council) silẹ fun Alakoso Ijọba Iwọ-Orun, ko si ni wa si Ipade Igbimọ Iriju na mọ.

(d) pe ayafi fun idabobo anfani awọn Oyinbo Oniṣẹ Ijọba ti mba iṣẹ lọ nitori aibumọ boya ede-aiyede kan le ṣelẹ. Agbara aṣẹ ileke ti o ti jẹ ti Gomina tẹlẹ ri yio pare.

(e) pe Ọba'birin Gẹẹsi ko ni ni agbara lati da eto ofin Iṣelu Ipinlẹ duro.

(ẹ) pe lati inu awọn memba aṣofin Ijọba ni nwọn a ti ma a yan Alamojuto Ofin (Attorney-General), o si ni lati ma a joko ni Igbimọ Iriju Ijọba.

(f) pe Oga-agba ti o ma a ba awọn arufin rojo ni lati jẹ oniṣẹ Ijọba ti a o yan ma a ṣe gbogbo eto ejọ ọdaran.

### Ọmọ Gọta di Oniya

IBADAN.

NI arọ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹta oṣu kẹwa ọdun yi ni ẹkunrin kan ri ọmọ okurin kekere kan ti ngmi fukẹ-fukẹ gbe ninu ẹjẹ ni gọta lẹba ọja Gẹgẹ ni Ibadan. O si gbe ọmọ na lọ si ile-alaisan (hospital) fun itọju lai mọ tani o bi ọmọ na. Ọmọ ti o ti fẹrẹ ku yi si gbadun lẹhin itọju atata ti nwọn fun un.

Nigbati o di ọsan ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu kanna ni obirin kan ọmọ Ileṣa ti njẹ Ọmọpe, ọmọ ọdun mẹrindinlogun wa jẹwọ pe on ni on bi ọmọ na ni ile itọju-alaisan, o ni on ti o mu on gbe ọmọ na si gọta nipe ko ni baba, on ko si le nikan ma a toju iru ọmọ bẹ ẹ. Ni nwọn ba npariwo le e gee.

Nwọn kọ ti gbe ọmọ na fun un, nwọn ni ki obirin na si ma a wa titi awọn yio fi ru ọrọ na daradara ki awọn to gba lati gbe ọmọ na sile.





## OLYMPIC GAMES
## Melbourne 1956



## Awon omo Sepeteri be Oloto wo

# IPADE EGBE OMO - ODUDUWA NI SHAGAMU











## Ola ilu Ipee nko'we

### AKIYESI PATAKI




## Egbe Afenifere l'owo dabira ni Akure

## AKIYESI



